# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 877 LAGOS SATURDAY JULY 13 JULY 19 KOBO MEJI (2D) 1963


Owo Ori Ni Tabi ...?

# Awon Tisa Kan Wo Gawu Lori Owo Ososu Won

ABA—Odunrun awon enia ti nwọn nṣe iṣẹ tisa labẹ awọn Ijọ Ṣọṣi ti nwọn npe ni Presbytarian Mission ni awon oga ijọ Ṣọṣi na ti ha iwe idaduro fun wipe ti esu yi ba ti pari ki nwọn joko sile wọn ko si iṣẹ fun oni mọ nitori esu ṣile kọkan lori ọọnun kọkan ti nwọn ni ki nwọn ma da ni owo ani fun iranlọwọ Ṣọṣi ti nwọn nṣe iṣẹ fun na ti awọn tiṣa na fjake kọri wipe awọn ko da esu a-da-ko.

A gbọ wipe awon tiṣa na ti kọwe ẹbẹ ranṣẹ si ẹgbẹ awọn oniṣẹ tiṣa wipe ki nwọn gba awọn lori ọrọ na. Alufa Ijọ na, Ọgbẹni Ochu Mbila ni awọn tiṣa kan ti gba lati san owo na, sugbọn awọn tiṣa ti nwọn ko lati san an ni awon Ijọ fẹ da duro; o ni ni ipade nla ti nwọn ṣe ni Calabar ni awọn ijọ Ṣọṣi awọn ti paṣẹ na, kiṣe adaṣe ẹnikanṣoso rara.

Iku Doro!

# 'Segun Omo Oloye Awolowo D'Ologbe

IBADAN—Agbọ jẹ igba sile ni gbogbo awọn ilu ni igun mẹrẹrin Nigeria ti gbọ iku Ọgbẹni 'Ṣẹgun Awolọwọ, akọbi ọmọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti o pade agbako iku moto lojiji ni kutukutu owurọ ijẹrin ni Abule ABANLA lari Ibadan si Shagamu nigbati o mbọ wa si Eko pẹlu dẹrẹba awamọto rẹ ti o jalaisi pẹlu re lojukanna.

Gbara ti jamba na tiṣẹ nibiti awọn atura ṣe ijọba gbe ntun ọna ṣe ni awọn ero inu mọto akero miran ti o ba wọn nibẹ ti ran wọn lọwọ lati gbe 'Ṣẹgun lọ si ile awọn alaisan ni Ade-Ọyọ-ibusọ maili (mile) mẹtala nsi sibẹ.

Gbogbo awọn dokita ti nwọn ba lẹnu iṣẹ lọjọna si bẹrẹsi sare sihin, sare sọhun lati gba ẹmi ọdọmọdekunrin na la nitoripe o ti farapa pupọ ju, ẹjẹ si pọ ti o njade lara rẹ. Nigbati yio fi to wakati kan ti nwọn ti gbe e de ibẹ ni o dakẹ.

(wo iyoku loju ewe keji)



**Iku doro! Iku pomo kekere jojolo. Awon aburo ologbe 'Segun Awolowo ni nwon mu iyepe sibi inoji re lojo ti nwon nsin ku re ni Ikenne.**

# Iku Omo Awolowo

(o bẹrẹ lati oju ewe kiani)

Akọwe Onirohin wa ni ere ni awada ni ni awọn ara Ibadan ti irohin na ko tasi leti wọn pe e, ṣugbọn nigbati o to agogo mẹkanla ti ẹrọ asọrọmagbesi redio tufọ na fun gbogbo araiye gbogbo ilu Ibadan pa rọrọ, awọn akọwe ti nwọn nkọwe lọwọ ninu ile iṣẹ Ijọba ju iwe ọwọ wọn silẹ ati kalamu ti nwọn fi nkọwe na.

Ọrọ wa di bi o ko lọ ki o yago lọna, gbogbo awọn obinrin Agbeni ti nwọn ṣẹṣẹ patẹ ọja wọn silẹ ni nwọn sare palẹmọ, ti olukuluku wọn kawọ leri ti nwọn ngbe ara sanlẹ, ti nwọn nsọkun gba ọna ile awọn alaisan Adeọyọ lọ.

Nigbati okiki iku ọmọ Oloye Awolọwọ na kan de GBAGI ati ọja L'UGBẸ'.nṣe ni gbogbo awọn ti o wa lọja na rọ giri ti olukuluku nsare wọ takisi (taxi) ti nwọn gba ọna ibiti nwọn gbe oku ọdọmọde na si lati le mọ bi irọ ni tabi otitọ ni ọrọ iku ọmọ na.


## Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogun ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wa ninu ile ipamọ owo, ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de' gba.

'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'

Barclays Bank ti se opolopo aworan oni sinima ti a ti mọ dada to si nderin pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Eyi jamọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti wọn ko eso oko wọn lọsi ọja. Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.



Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe o ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nya owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gba rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ ibusun, sugbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kokoro tun jẹ iyokù.
Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.
Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tarata sile Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ owo nibẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*




## Ati l'Eko

Gbara ti awọn enia ti gbọ l'Eko ni gbogbo gwọn obinrin alaṣọ l'Eko ti palẹmọ ti ọpọlọpọ wọn gba ọna odan lọ lati lọ ba Oloye Awolọwọ kẹdun ninu ọgba ẹwọn ti awọn ọlọpa da a duro si lati igba ti nwọn ti mba a nro ẹjọ ọlọtẹ.

Nigbati nwọn de ibẹ, enia pọ tobẹgẹ ti ẹru fi ba awọn dẹreba ti o ntọju awọn ẹlẹwọn ti nwọn ko fi jẹki wọn wọle lati ri Oloye Awolọwọ a fi awọn diẹ ninu awọn enia pataki ni nwọn je ki nwọn wọle lati lọ ba baba ọmọ na kẹdun, ninu wọn ni Alufa (Rev.) F O Sẹgun, Alufa ṣọṣi nla ni Ẹhingbẹti l'Eko pẹlu Lọya Abraham Adesanya ati awọn enia miran.

## Iwe Ibakedun

Lẹhin eyi ni awọn ọga ile ẹlẹwọn na ba fi waya pe awọn ọlọpa wipe ki nwọn jọwọ wa ba awọn le ogunlọgọ enia ti o pe si ẹnu ọna a ti wọle ọgba awọn ẹlẹwọn lọ.

O ju ẹdẹgbẹta waya iwe ibakẹdun ti Oloye Awolọwọ ri gba lati ọwọ orisirisi enia ni ijẹrin bẹni awọn alabakẹdun na si tun nfi iwe waya ranṣẹ lati oke Okun pẹlu ilu Oyinbo titi di oni ọjọ Satide ti iwe yi jade.

Ninu awọn enia patataki ti nwọn fi iwe ibakẹdun ranṣẹ si Oloye Awolọwọ na ni Gomina-agba Ọlọla Dokita Azikiwe, Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọṣe (lati Bauchi ilu rẹ ni o ti tẹ waya tirẹ ranṣẹ),

(We yoku loju ewe kẹjọ)

## Ole Ki Gbe Kakaki :

# Awon Olosa Mekaniki Gbe Moto Titus Lo N'Ijaiye

ABẸOKUTA—Ole ki gbe kaki la gbọ, awọn ọlọṣa mẹkaniki Abẹokuta kan gbe mọto oni mọto lọ ni Agọ Ijaiye ni Abẹokuta laipẹ yi, ṣugbọn ọwọ awọn Ọlọpa ti tẹ wọn, nwọn si ti ko wọn wa si iwaju adajọ Kotu ni Iṣabọ ni ọsẹ ti o kọja yi, orukọ awọn mẹta ti nwọn ri mu nipa mọto akero ti nwọn sọ wipe nwọn ji na ni Ezekiel Adeyẹmi (ara Iporo Ake) Atanda Samuel ati Aminu Olowoake (mẹkaniki Idi Apẹ).

Gẹgẹbi akọwe onirohin Eleti-Ọfẹ ti gbọ iroh n na si lọdọ ẹnikan ninu awọn ọtẹlẹmuyẹn ọlọpa ti o lọ gbogun ti awọn ọlọṣa ti o ji mọto-akero na ninu igbo ti nwọn lọ gbee pamọ si; Ọgbẹni Titus Kẹhinde ọmọ Agọ Ijaiye ni ẹniti o ni moto-akero (5 ton Morris) WE 665 na ti nwọn gbe lọ, o si npe ni HOPE TRANSPORT.

Dẹrẹba ọmọ Agọ Ika kan ni o nwa mọto na fun ẹniti o nii, nwọn a si ma fi ko ero lati Abẹokuta wa si Eko, nigba miran nwọn a ma ko ero gba Ibadan lọ.

Lọjọ ti nkan yi ṣẹ ẹ, oru a ẹ ọjọ Jimọ mọ Satide ni, bi awọn onimọto na ti gbe mọto wọn ti ọna oko de, nwọn gbe si ojude onimọto na ni ita AGBARO leti Ṣọọṣi Baptist ni Ijaiye, ibẹ ni nwọn si nma gbee si lati igbati ti Titus onimọto yi ti ra a, nkankan ki si ṣee nibẹ.

A fi igba ti o di owurọ ọjọ Abamẹta (Satide) ti awọn onimọto de ibiti mọto nsun, ti nwọn ni ki awọn gbee jade lati lọ fi ṣe iṣẹ oojọ wọn, ti nwọn si fẹẹ ku. Ere ni, awada ni, Titus ba lọgun "IBOSI! NWỌN GBE MI NI MỌTO LỌ."

Nwọn wa bẹrẹsi wa mọto na gba igbo Ijẹlu kakiri, a jẹ ninu igbo IGARA ni LANTORO ni Abẹokuta na ni awọn ọlọṣa na gbee pamọ si, ti nwọn wa nyọ gbogbo nkan ara rẹ ni ikọkan lọ si ibiti nwọn yio ti sọ wọn dowo, nibiti nwọn gbe tinṣe eleyi lọwọ ni awọn ọlọpa ti ba wọn ti nwọn ba fija pẹtu.

Awọn ọlọpa ti nwọn mba awọn ọlọṣa na ro ẹjọ yi ni ki Adajọ Oyinka Odumosun ti nwọn nṣe ẹjọ na niwaju rẹ ma ti gba iduro wọn nitoripe o tun ku awọn kan ninu awọn ọlọṣa na ti nwọn fẹ ko wa si kotu.

---

# Adajo Feyi Fawon Leti . . .

EKO—Ni ọjọ ti awọn Ọlọpa ko Oloye Ọbafẹmi Awolowọ, olori awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) wa si Kotu ganran l'Eko pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ lati bẹ rẹsi ro ẹjọ ẹsun ti awọn ọlọpa ni nwọn di ẹ mọlu ilu Oyinbo, awọn enia ti nwọn wa si kotu na ni Ọdan ti nwọn ko ri a e wọle pọ bi iyanrin okun.

O di oṣu kẹjọ ninu oṣu ti a wa yi; awọn ẹni mẹkanlelogbọn ni awọn Ọlọpa ti Ijọba mu wa si agbegbe Kotu yi ko lẹjọ na, ẹsun ti nwọn fi wọn sun niwaju adajọ Kotu awọn ọlọpa ti nwọn ko wọ i lọna ni wipe, nwọn fẹ da ijangbọn silẹ.

Nigbati nwọn ro ẹjọ na titi, adajọ ti nwọn ro ẹjọ na niwaju rẹ ni on ri wipe awọn ọdaran na jẹbi ṣugbọn on yio fi eyi fa wọn leti, on ko ni fiya kan jẹ wọn rara ju wipe nwọn ko gbọdọ ṣe ijangbọn kan rara larin oṣu mẹfa. Awọn ọlọpa si towọ wọn bọwe lori ọrọ na.

---

BE TALLER
Increase your Height.
Details free Add:-
C. T. Hospital, Azad Market,
Delhi 6, India

---

# Nwon Ti Gbejo 'Aunti Koforun' Lo Si Kotu Nla

LONDON—Gẹgẹbi a ti sọ fun ẹnyin ọkawe Eleti-Ofẹ ni ọsẹ ti o kọja wipe ẹ o ma gbọ bi awọn ọlọpa ilu Oyinbo ba ti ro ẹjọ Dokita Stephen Ward, ti nwọn ka ẹsun mẹjọ mọ lẹsẹ wipe o nfi awọn aunti Koforun ṣe iṣẹ panṣaga ati wipe o tun lọwọ ninu awọn mba wọ ṣe oyun, na si; eleyi ni ọrọ ti awọn ẹleri miran ti awọn ọlọpa ti nwọn mu a dokita na ṣejọ ro tun sọ.

Ọkunrin Oyinbo kan ni opolopọ igba ni on ma lọ si ile ti dokita Ward ra ngbe ni 17, Wimpole Mews ni London, o ni gbogbo igba ti on ba si ti dele dokita Ward a pe Omidan Keeler fun on, on a si ba a la. O ni gbogbo rẹ lori owo ni, dokita Ward ni on si nsan owo tun ti o nko o fun un.

Ọgbẹni na ni on ala a a ba awọn onibara lọdọ wọn, ati pe omoge miran tun wa lọdọ dokita na ti ko nṣe ọmọge Keeler.

Ki adajọ Kotu na to paṣẹ wipe ki nwọn gbe ẹjọ na lọ si iwaju adajọ agba ni Kotu nla ti Old Bailey lati lọ ro o ni ẹkun-rẹrẹ, Obinrin Oyinbo kan ti o tun ro ẹjọ ni on fi igba kan lo yun lọdọ dokita Ward ninu ile rẹ ni nwọn ti ba on ṣe oyun na danu.

Nwọn ti gba iduro Dokita Ward, a gbọ wipe awọn yio bẹrẹ ẹjọ ra lati ma ro o ni kotu nla ninu oṣu ti mbọ (August) yi.

---

## Akiyesi

..Nitoto Oja Ko Ta Ni Akoko ti a Wa yi...

Sugbon aita oja ko si fun awon ti nwon npolowo oja won sinu iwe . .

Irohin ELETI-OFE ni osose.

Kowe Ipolowo Oja tire ranse si:
ELETI-OFE,

28, KOSOKO STREET, LAGOS.

# ELETI–OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAM "ELETI-ỌFẸ" LAGOS Phone 23370
VOL XIV. N0, 877 STURDY JULY 13 — JULY 19 1963

## Oro Olotu:

# Iku Doro! Iku S'eka!!

Ọfọ nla kan ti o ṣẹ gbogbo ilẹ Nigeria ninu ọsẹ yi ni ti ọdọmọde kan ti nwọn npe ni Ṣẹgun Awolọwọ tiṣe akọbi Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifere (AG) ti a gbọ irohin ni owurọ ijẹrin ọjọ'Ru wipe o pade agbako iku loju ọna mọto nigbati o nwa iṣẹ oojọ rẹ lo ni ọna Ijebu.

Nitotọ iku ti di meji epinni ninu igba ti a wa yi, ṣugbọn ko nṣe irufẹ awọn ọdọmọde jojolo bi iru 'Ṣẹgun yi ni a ngbadura fun wipe ki nwọn ṣanku mọ wa loju nitoripe awọn ni a fi ọkan tẹ gẹgẹbi OPOMULERO ilẹ wa ni ode ọla. Ha, iku!

Kinni ki awọn obi rẹ ro? Ti owo gọbọyi ti awọn na lee lori ni, tabi aisun, tabi aiwo pẹlu ọpọlọpọ wahala wọn lori rẹ lati igbati o ti wa ni ikoko ti o fi dagba toju bọ?

Awa onirohin Eleti-Ọfẹ fi tẹdun tẹdun ọkan ba awọn obi ologbe ọmọ na kẹdun, adura wa si ni wipe ki Ọlọrun Olodumare ki o tu wọn ninu, ki o si da awọn iyoku si. Ọfọ ti o ṣẹ wọn yi, ọfọ gbogbo ilu ni.

A! Iku doro! Iku doro !! Iku mu Opomulero lọ!

# Ore Die, Ota Die Ko dara

Pẹlu inu didun ati ayọ ni gbogbo awọn enia ti nwọn wa ni igun mẹrẹrin Iwọ Orun ilẹ Nigeria fi gba irohin wipe awọn ẹgbẹ oṣelu ti o wa ni agbeghe yi ti se pinu lati so ọwọ pọ lati jumọ ṣe pọ fun itẹsiwaju ati ilọriwaju Ijọba wọn.

Bi a ba deju ti a ri imu a o ri wipe gbẹfẹ ni awọn ti o nṣe Ijọba agbegbe Ariwa ati awọn oṣelu Ijọba Ila Orun mba Ijọba wọn bọ lati nkan bi ọdun kẹrin sẹhin wa, ṣugbọn tẹmbẹlẹkun oriṣiriṣi ti fidi mulẹ ninu Ijọba Iwọ-orun eyi ti o ti mu oniruru ede aiyede wa sarin awọn oṣelu wa.

Bi a ti gba wipe ko si ohun kan ti Oluwa Ọlọrun ko le ṣe nitori wipe o ri ohun gbogbo, o si le ṣe ohun gbogbo.

Idunu ni fun awa Eleti-Ọfẹ wipe gbogbo rogbodiyan ede aiyede nu fẹ pari ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi, ṣugbọn a sẹ yin wa a sẹ yin bọ, ni a mgbọ wipe awọn alakatakiti kan ninu ẹgbẹ N. C. N. C. ati Action Group tun fẹ ina eto rere na pa, eyiyini o fa sababi ti awọn Lọbalọba fi ti ẹsẹ bọ sokoto nitoripe "Agba ki wa ni ọja ki ori ọmọ tuntun pa" (ki eleyi jẹ owe ti awọn agbalagba) wipe ki gbogbo awọn oṣelu wa so ọwọ pọ dara, ohun pataki kan ti o fi oju han ninu rekerudo ti o-kọjalọ yi ni wipe o ta die. ORE Diẹ ni awọn oṣelu wa ti owa ni Iwọ-orun mba ara wọn ṣe.

ỌTA Diẹ ORE Diẹ Ko dara.

# Iwe Si Olotu

## EYI WU WA..

Ẹ Jọwọ, Olotu ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe irohin yin oloyin mọmọ lati ba awọn oṣelu Nigeria sọrọ ọmọlẹbi diẹ nipa ija edeaiyede ti o ti mba nkan jẹ fun wa paapa awọn Yoruba apa Ila orun.

Gbogbo bi nkan ti nlọ si larin awọn ẹgbẹ oṣelu na lati nkan bi ọdun kan ati abọ ko dun mọ awa ara wọn ti a wa ni ẹhin odi ninu ara.

Ara ile mi mọ ọ ni amodi, arun ni awọn ara ita ipe e.

Inu wa dun lati gbọ wipe nwọn fẹ pari edeaiyede na; Ọlọrun yio si ba wọn lọwọ si i, ṣugbọn o yẹ ki awọn Yoruba ye rikiṣi ara wọn se ti nwọn fẹ ki awọn ọmọ ti nwọn bi silẹ ki nwọn le gbadun aiye wọn lẹhin ọla.

Emi ni,

A. Alawiye

Cotonou,
Dahomey

## Ijoba Ajumose ?

Ẹ gba mi laye lati kan saara si awọn agbalagba oṣelu wa ti nwọn ro wipe o dara lati jiroro lori ọrọ edeaiyede ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ-orun ati pe o yẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ UPP ati AG ki nwọn da Ijọba Ajumọṣe kan silẹ fun ilọsiwaju ipinlẹ na.

Eyi wu wa pupọ, ṣaṣa ni ọmọ ilẹ Yoruba ti yi o sọ wipe imọran ki a jọ rin pọ yi ko dara nitoripe nkan buruku ni ọtẹ ma nda silẹ larin ilu.

Nkankan ni o si nmimi lọkan, iyẹn ni ti awọn alayinsi ti nwọn ko ni fẹ ki nkan na toro, ṣugbọn ki a foju silẹ ki a si ma worun, ki a si tun ma gbadura ki Ọlọrun bawa lọwọ si ọrọ awọn oṣelu na,

Emi ni

Abẹokuta Y. Akọgun

# Awon Igbomina Fe Jiroro Lori Ihale Alhaji Dalhatu Bida

EKO—Lori ọrọ ihalẹ kan ti nwọn sọ wipe Kọmisọnna ti nwọn ṣẹṣẹ yan si ilu Ilọrin, ti nwọn npe oruko rẹ ni Alhaji Dalhatu Bida, nhalẹ kiri nigbati o lọ bẹ agbegbe ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti wo pẹlu awọn ara Ilọrin diẹ ti o tẹle e lẹhin ni a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ fẹ ṣe ipade kan le lori lati le kọ iwe sọwọ si Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto ti ṣe Olotu Ijọba Ariwa wipe ki o kojanu Kọmisọna yi nitoripe alafia ni awọn nfẹ ni agbegbe Ilọrin pẹlu awọn Igbomina.

Eyi ni ọrọ diẹ ti o wa ninu iwe a-pin-kakiri kan ti ọmọ Esiẹ Igbomina kan tẹ jade, ti nwọn nha kakiri nipa ọrọ alufansa ati ẹnu atẹ ti Komisọna na (Alhaji Bida) nsọ kiri nipa ọrọ ipinlẹ ti awọn Igbomina ni awọn nlẹ.

O ya, ẹ ma ka a niṣo:

### Iberu Ko si fun Igbomina, Offa ati Ekiti mo, E ye Hale

'Laipẹ yi ni mo gbọ pe adele komisọnna (Commissioner) fun ilu Ilọrin Alhaji Dalhatu Dida ṣe ibẹwo irin ajo lọ si ile Igbomina, Ọffa ati Ekiti, pẹlu awọn ara Ilọrin diẹ ti o tẹle lo si irin ajo na.

Ninn ọrọ Alhaji Dalhatu Dida si awọn enia ilẹ nwọn yi, o nhalẹ, o si nbu ẹnu atẹ lu ọrọ Division fun agbegbe wọnyi, laise aniani o han gbangba pe iṣẹ ti Ilọrin ran Alhaji Bida lo njẹ ati pe ki agbegbe kọkan ba Ilọrin fi ọwọ sowọpọ, ki wọn ma ṣe ni ẹmi pe Ijọba ilẹ Ariwa yio da ipinlẹ titun miran silẹ ni ilẹ Ilọriu ati pe ko si ninu eto Ipinlẹ ilẹ Ariwa pe awọn yio da ipinlẹ titun miran silẹ ni ilẹ Ilọrin, nitoripe ki awọn ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti maṣe gbọ ọrẹ ti awọn oṣelu raurau nsọ kakiri, o si nfi ye awọn ọba pe a ntan nwọnjẹ lati gba ipo wọn ni, ọrọ buruku patapata ni Alhaji Bida sọ,

'Awọn Yoruba ma npa owe kan ole enia ni nwọn si ma nfi owe na bawi

(wo iyoku ni oju ewe kejọ)

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Ko Ni Baje

Ni ọsẹ ti o kọja ni mo bẹ gbogbo ẹnyin ọkawe mi wipe ki ẹ ṣe gafara fun mi nitoripe ọrọ mi ko ni po ati pe nko fẹ sọ oboto lori ọrọ awọn oṣelu wa ti nwọn fẹ da ere pọ ki awọn maṣe bi ti atijọ nitoripe ọpọlọpọ nkan ni i,a ọ na mbajẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun nisisiyi.

Mo ni ọbẹ ki tinu agba mi, ẹnu emi Ayiluka kọ ni ẹ o ti gbọ wipe iya Kọla lajẹ; ṣugbọn ẹnyin ọrẹ mi aiye ko ni bajẹ nigbati wa. Kinnişe ti awọn oṣelu wa ko ni ọrọ kan iṣẹnu? Tabi nwọn ko tilẹ mọ wipe awọn ara ilu miran ti nfi n wa ni orukọ nilu okere? Nwọn ni ti sọ iṣẹ oṣelu di jẹun jẹun.

Awọn kan?wati nwọn pe ara wọn ni ọmọ Yoruba ti awọn ko fẹ ki rogbodiyan ti o wa nilẹ na pari rara nitoripe ninu makaru yi ni awọn nri jẹ. O da bi ẹni wipe ti ọrọ na ba pari tan ẹnikan kọ ni mọ wọn mọ nipa ọrọ iṣelu,

### Tembelekun

Mo fẹ ki ẹ ba mi ka ọrọ Olotu Eleti-Ọfẹ ti o sọ nipa awọn ọlọtẹ oṣelu wa nigba kan lori ọrọ rogbodiyan ti o delẹ yi:

"LAIṢE iye meji, ẹnyin ọkawe wa a kiyesi wipe lati iwọn nkan bi oṣu kan wa ni awọn kan ti a le pe orukọ wọn ni ALAWIYE ti bẹrẹ si kọ alaye ọrọ sinu iwe irohin wa. O bẹrẹ lati ọdọ Ọmọ Ọbanta lati Ijẹbu Ode Ọmọ Lisabi lati Abẹokuta ilu Ẹgba sọ tirẹ, Alẹri ọmọ Hausa paapa ṣe Waasi tirẹ; "Ẹrukobodo" ni kiloṣubu lu on, Ọmọ Onikoyi (ọmọ Eko) ni ki nwọn maṣe fọwọ rọ on sẹhin.

### Ija

"Ọrọ awọn Alawiye wa lọtun losi fa kiki, iyẹn ni wipe ọrọ pọ nibẹ nitoripe nigbati Ọbanta (Ijẹbu) yio pari tirẹ, o ni ni ọdọ awọn Ijẹbu ni ọtẹ ati tẹntẹlẹkun gbe pin si. O ni orin ni ṣaju ọtẹ, awọn si mọọ kọ de opin; awọn ni awọn da orin-ọtẹ "Gedegbe l'Eko wa" silẹ, nitotọ na nwọn si ya ilu Eko na ni ilẹ Yoruba.

ẸGBA ọmọ LIṢAAI lati Abẹokuta ni awọn korira ọtẹ nitoripe akuko ti kọ awọn pe ọtẹ ko mbi ọmọ ni abiye; afi abiku ni bi; rukerudo ati ija-igboro ni o nda silẹ. O ni bi edeaiyede ba si ti de, o yẹ ki a pe Aro inu wa ati ọdọfin inu wa ki a mọ ọna ti ao gbee gba ki a ma le di ẹni-ẹhin lọla.

"Ẹrukboodo" (ni Ifẹ ọmọ Oduduwa) kigbe wipe asiko to! gbogbo ẹnyin Yoruba, ẹ parapọ ki baba iya ma ba le jẹ wa. O ni on ko ṣọ ọrọ on "lati wa ọmọ kun ọmọ lẹhin Oloye Awolọwọ, bẹni ki iṣe wipe ino nsọ ọ lati le fi le en a kuro lẹhin Oloye Akintọla.

### Ko D'ola

"ỌmỌ ONIKOYI (ọmọ Eko) ni niti awọn, awọn kiṣe ọdalẹ enia ṣugbọn ko tọ, ko si yẹ ki awọn ṣe ọrọ ibatan awọn na ni ọrọ onigba ni o ape igba rẹ ni aakara ti a fi baa ko ilẹ nitoripe "bi iya-nla ba gbe ni saalẹ iya kekere a mọ gun ori-ẹni".

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)




Comfortable and safe

A roomy 5-6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety; these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS: (E.B.) IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT-HARCOURT: ABA.

Sub—Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

## Ilu Ghana Mba Minista Won Kan Sejo

ACCRA-Ogbeni Ako Adjei tise minista alaboiuto eto okere aigb'a kanri ti awon olopa ilu Aganyin mba sejo wipe o ji Ijoba lowo ni adajo Kotu awon olopa na pase fun wipe ki nwon gbe ejo re lo si Kotu-ganran fun riro ni kikun.

Esun ti awon Olopa fi i sun ni wipe o fi igba kan gba okekan le egbedogbon ponun (£52,000) ni Banki Ijoba wipe on fe lo o lati gbo asiri kan lati awon ilu okere fun Ijoba on, a je iro ni o npa.

Oga awon agbejoro Ijoba Ghana, Ogbeni Kwan Swanzy, ni nigbati awon bi odaran minista yi ni ogba ewon ti nwon ti fi ramo si lati esin, o ni ise ... ni ... owo na fun aitonpe ... kan ti ... 'ZEBUS' ti so wipe ona se eda ni ou ni lati fi lowo ninu aiye on.

# Alhaji Kan Fi Gbese Lo Si Meka N'Ijebu-Ode

IJEBU-ODE—A ki fi gbese seso, sugbon awon onile ifowo pamo kan ti oruko ile ise won nje Barclays Bank ni Ijebu-Ode ni gbese ni Ogbeni Alhaji kan ti oruko re nje B A Aliyu fi lo si Meka ati Medina tire.

Loya awon Banki na ti o fi iwe ipejo ru Alhaji Aliyu na wa si Kotu fun gbese a ni egberun ponun (£1,000) ni owo-ele ti Alhaji na gba lowo Barclays Bank nigbati o fe lo si Meka, ponun merinlelogoji pelu sile mejila ni ele eri owo na.

Loya yi tun se alaye fun adajo wipe awon kowe bere owo yi lowo Alhaji yi titi ko dawon lohun, o ni eyi lo je ki awon woo wa si Kotu wipe ki o wa san an.

Alhaji Aliyu paapa gba loya, loya re na ni ki nwon ba awon so oga na se, o ni Alhaji na ti gba lati ma san gbese na n ponun mewa mewa ni ososu titi yio fi san an tan.

Loya ti awon Banki na gba faake kori, o ni awon ko gba ponun mewa sandie-die yi rara, awon nfe owo na ni kiakia ni. Loya Alhaji na ni ki nwon ko kuku fun awon laye ki awon ba awon oga Banki na soo boya nwon le gba wipe ki awon ma san an die die nitori o vo ko si nilu rara nisisiyi.

## Oku Omo ... li-ou Pali Biya

EKO—Oju a ri to nilu Eko ti a wa yi, lowuro ojo ... ni awon ara Epetedo ji l'Eko ni nwon ba oku omokekere jojolo kan ti nwon sese bi ti nwon di ... sinu Pali biya (beer) ti nwon ju sita gbangba.

Gegebi awon alafojuri ti nwon ri oku omo ikoko na nibiti nwon gbe gbe e ju si ni oju ... ti Oshodi l'Eko, nwon ni ninu aso kan ni nwon di omo na si ki nwon wa gbe e sibe.

Ijoba ni awon ko mo oruko iya omo na Sugbon nwon ti gbe oku omo na lo sile awon lakuku fun abewo.

# Eleti-Ofe D'araba

## Iwo Le Se Bayi ? Ki O Gboruka Arede Lowo Aro ?

DURHAM— Awon Oyinbo a ma pa owe kan bayi wipe ife foju, boya iru ife afoju iru eyi ni o mu omodebinrin arewa kan ti awon npe ni Rhoda Walls, eni odun mokanlelogun ni ilu Oyinbo gba oruka arede lowo okunrin kan ti nwon npe ni Robert Bennett ti o gbe e ni iyawo ninu Sosi kan laipe yi.

Nkan ti o wa ninu oro awon toko taya na ti o e iyanu pataki fun ... gbo eni ti o gbo oro rede won na ni ipo ti oko iyawo yi wa ti nwon fi gbarede— o ro lati ibadi de ile.

A gbo wipe o ku nkan bi osu merin ti awon meji ni lati gbarede ni ojo iyawo oju ona yi pade agbako, ti o subu lori oke ibiti o gbe ti nse ise nwedu lori oke kan ti nwon npe ni Wheatley. Eleyi mu ki o di aro opapan odo lojiji. Ko ro lowo, sugbon gbogbo nkan ti o bere lati ibadi re ro patapata, ko si le dide dumo.

Eleyi ko mu ki awon ye ojo igbeyawo re na ti nwon fe se. Dipo ki toko taya wo moto ayokę, ibusun-alarun (Stretcher) ni nwon fi ru oko lo si Sosi (Methodist) ni Hexham West and ni ilu Durham; gbogbo awon ti nwon fiwe pe ni nwon pe sibi isin iyawo na.

Idubule ni oko iyawo yi wa niwaju alufa titi ti nwon fi se isin na tan, ti nwon fi fi oruka arede bo iyawo arewa yi lowo. Oko iyawo paapa se ibura lori ibusun-alarun (stretcher) ti o dubule si.

Se iwo le se be, ki nwon fa e foko aro ? Sugbon omoge Rhoda ti gba kamu, o ti ko eru re lo si ile Robert ARO oko re.

## IKEDE FUN GBOGBO ENIA

Awon ebi Oloye Oluwa se ikede yi fun gbogbo awon ti o haya ile lowo won ni Apapa wipe gegebi iwe adehun, olukuluku won ni lati ko ile sori awon ile na larin odun kan ti nwon ba ti gba ile na.

Gbogbo ile ti nwon ba gba ti nwon ko kole si lehin odun kan a pada sowo awon ebi yi, a fi bi o ba nidi pataki ti mehaya na ko fi se be.

Gbogbo ile ti nwon ba ti ko ni abo abo sile ju odun meji lo ti nwon ko ba pari won larin ose meji ti iwe ikede yi jade a je wipe nwon ko fe lo ile na mo niyen, awon ile na a pada di tawon onile pada.

Gbogbo awon ti nwon ba ri wipe ikede yi ba awon wi ki nwon wa si ile ise wa pelu awon iwe adehun ti o ba wa lowo won lati wa foju kan wa. Ojo keji osu July 1963 ni a se ikede yi.

**R.A. Oluwa,**
Oloye Oluwa ti Eko ati Apapa.
**Ashafa Oluwa,**
Asoju awon Ebi Oloye Oluwa.

British Churches' Call

# Day Of Prayer For South Africa

LONDON — A joint statement calling for a day of prayer on Sunday, July 21, for the beginning of intercessions for South Africa is issued today, signed by the heads of all Christian denominations in Britain.

The statement says that recent legislation in South Africa goes even further towards removing "one of the main foundations on which civilisation is built, namely the liberty of the individual.

Unless there was a reversal of this trend "we can see nothing in the end but violent disaster' said the signatories.

"We beg the present rulers to take heed before it is too late and we express the most urgent hope that patience will yet prevail among the non-European population."

What could Christains in Britain do, they asked: "First we can pray-for all in South Africa- the black, coloured, Indian and white people and their leaders." It was hoped that July 21 might be a day of beginning and that prayers would continue "without ceasing" in churches and homes.

"Secondly we can aid with our money those who suffer from the impact of the repressive legislation', the statement goes on.

"Thirdly, as citizens, we can make it clear that we recognize Britain's resposibility for three High Commission territories, Basutoland, Bechuanaland Protectorate and Swaziland. Until they reach viable independence we must ensure that the Government in Britain continues to be responsible....

The statement is signed by the Archbishops of Canterbury and York, the Moderator of the Church of Scotland, the Archbishop of Birmingham on behalf of the Roman Catholic hierarchy, the President of the Methodist Conference the Chairman of the congregational union of England and Wales, the President of the Baptist Union, the Moderator of the General Assembly of the Presbyterian Church of England, the Moderator of the Free Church Federal Council, and the General Secretary of the British Council of Churches.

## Tax Officer Looks Forward To Working In Nigeria

LONDON — Mr. Michael Brommell, a 27-yeras-old British income tax officer, sailed from Britain on Friday to spend three years in Nigeria, where he is to help in organising a system for the training of tax officers in the Northern Region, under Nigeria/UK. technical assistance arrangements.

'I am very pleased that I have so selected for this exciting assignment and I am looking forward very much to be the challenge and opportunities of a new line of country,' Mr. Brommell told our correspondent just before sailing.

Mr Brommell will be one of a team of three Britons engaged on the project, at Zaria Institute. The other two are Mr B Jones an Inspector of Taxes, and Mr P Ayres, a tax officer. Mr. Brommell will be assisting in the training of Nigerians, the preparation of training manuals and official instruction books, and in the design of official forms.

He has been an income tax official in Nottingham since he left school at the age of sixteen. He is marred and his wife and daughter aged twenty-two months will be accompanying him.

## Nigerian Students On English Farm



**Modern milking machines were one of the many mechanical aids that interested these two Nigerian students when they visited an English farm recently. Mrs. E A Fagunwa and Mr. M M Bida are at present at colleges in Britain, but during the three-weeks Easter end-of term holiday they have been touring they north of England under the auspices of the British Council.**

# Young British Table-Tennis Champion For Nigeria

CHESTER BARNES, 16—year-old British table-tennis champion, arrived by air at Ikẹja yesterday evening, to begin a series of exhibition tournaments in Lagos, Ibadan, Kaduna, and it is hoped, Enugu.

His tour has been paid for and arranged by the Nigeria Table Tennis Association.

Barnes' first appearance in Lagos will be with Zoltan Berczik of Hungary, the ex-European table-tennis champion, in a tournament with Nigerian table-tennis stars, at King's College on Saturday afternoon, at 3 30 p.m.

